# ỌBA JUDA TI O KẸYIN ATI IGBEKUN JUDA

**2 Kronika 36:11-21; Jeremiah 25:1-33; 28:1-17; 29:8-14;**

**39:4-8**

## ẸKỌ 375 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ẹnyin o si ṣafẹri mi, ẹ o si ri mi, nitori ẹ o fi gbogbo ọkàn nyin wá mi" (Jeremiah 29:13).**

### Ipo Ibi ni Juda

A mọ̀ Jeremiah gẹgẹ bi Wolii ẹlẹkun. O jẹ ẹnikan ti o ni iwuwo ọkàn fun awọn eniyan Ọlọrun. O fi gbogbo ọjọ ayé rẹ̀ fun igbiyanju lati ran awọn ẹlomiran lọwọ, o si gbé iru igbesi-ayé ti Ọlọrun le fi maa ba a sọrọ, ki O si maa sọ ohun ti yoo ṣẹlẹ ni ọjọ iwaju fun un.

Ọlọrun ti ṣeleri fun awọn Ọmọ Israẹli nigba ti wọn jade kuro ni Egipti pe Oun yoo wà pẹlu wọn niwọn-igba ti wọn ba duro ti Oun, tabi ti wọn ba n gbọran si Oun lẹnu. Ṣugbọn O tun ṣeleri ijiya fun awọn ti kò gbọran pẹlu. Ọpọlọpọ iran awọn Ọmọ Israẹli ni o ti wá si aye ti wọn si kú lati igba naa, awọn wọnni si mọ̀ pe, ohun ti Ọlọrun ba wi ni O maa n ṣe: awọn ẹni rere ti gbadun ibukun Rẹ̀, awọn ẹni buburu si jẹ iya ti o tọ́ lati ọdọ Rẹ̀.

Nitori iwa buburu awọn eniyan naa, a pin awọn ẹya mejila lẹyin iku Sọlomọni. Mẹwaa ninu awọn ẹya naa ni a n pè ni Israẹli, meji ti o si kù ni a n pe ni Juda. Israẹli kò ni awọn ọba rere: nitori eyi ni a ṣe kó awọn ẹya mẹwaa nì ni ẹru, awọn keferi si fi ilẹ wọn ṣe ibugbe.

Awọn ọba rere diẹ ó wà ni Juda, awọn bi Asa, Hesekiah, Jehoṣafati, Ussiah, ati Josiah. Nitori tiwọn, Ọlọrun dá orilẹ-ède Juda si fun igba pipẹ diẹ si. Ayipada-si-rere nlánlà ti o ṣẹlẹ ni akoko ijọba Josiah ọba fa ibukun Ọlọrun sọkalẹ fun saa kan; ṣugbọn nigba ti Josiah kú, ireti kankan kò si fun Juda mọ́ lati di orilẹ-ède alagbara bi ko ṣe igba Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun. Awọn ọmọ ati awọn ibatan Josiah ti o jọba lẹyin rẹ̀ jẹ awọn eniyan buburu wọn kò si ṣe ire kan fun awọn eniyan naa. Gbogbo orilẹ-ède Juda patapata ni o joko sinu ẹ̀ṣẹ ati ipo oṣi, wọn n duro de ikolọ si oko-ẹrú.

### Akoso Nebukadnessari

Akoko yii gan ni Nebukadnessari jọba Babiloni, orilẹ-ède keferi nla. Ọlọrun pe Nebukadnessari ni iranṣẹ Oun. O si lo o lati jẹ Juda niyà.

Nigba ti awọn ọmọ-ogun Nebukadnessari kọlu Juda, awọn eniyan ti wọn dara ju lọ ni wọn ko lọ si Babiloni. (Ninu wọn ni a ri Daniẹli, Ṣadraki, Meṣaki, ati Abẹdnego). Awọn eniyan ti kò ni laari ni a fi silẹ ni ilẹ naa, a si fi awọn iran Josiah ṣe alakoso lori wọn.

Jeremiah kilọ fun awọn eniyan wọnyi lati gbọran si aṣẹ Nebukadnessari ki wọn si fi alaafia ba awọn alakoso ilẹ okeere yii gbé, ṣugbọn Sedekiah dà majẹmu rẹ̀ pẹlu ọba Babiloni naa, o si kọ ẹ̀yin si Ọlọrun. O kọ̀ lati tẹti si imọran ẹnikẹni.

### Sisọ Asọtẹlẹ Ọrọ "Didun-didun"

Bi o tilẹ jẹ pe Ọlọrun ti sọ fun Jeremiah pe kiko nigbekun lọ naa yoo pẹ to aadọrin ọdun, sibẹ wolii kan, Hananiah, dide, o si wi pe kiko nigbekun lọ naa yoo dopin laaarin ọdun meji. Awọn eniyan maa n saba fẹ gbọ "ihin ayọ" i baa ṣe otitọ tabi èké. Ni ọpọlọpọ igba ni a ti fi ileri alaafia tan awọn eniyan jẹ titi idà fi wa sori wọn, lẹyin ti o ti pẹ jù lati sá asala. Paulu Apọsteli kọ akọsilẹ pe ni akoko tiwa yii awọn eniyan yoo maa yí eti wọn pada kuro ninu otitọ, wọn o si yi pada si itan asan, nitori pe wọn kò le "gba ẹ̀kọ́" ti o yè koro."

I ba dun mọ́ Jeremiah ki isinru naa jẹ iwọn ọdun meji pere, ṣugbọn o mọ̀ pe awọn ọrọ wọnni ki i ṣe ọ̀rọ Ọlọrun. O sọtẹlẹ pe Hananiah yoo ku ni aipẹ, o si kú. Ṣugbọn Jeremiah wà laaye lati maa sọ Ọrọ Ọlọrun fun awọn eniyan.

### Aika Ọjọ Isinmi si

Nigba ti awọn Ọmọ Israẹli jade kuro ni Egipti, Ọlọrun ṣe ofin pe ọdun ikeje-ikeje ni lati jẹ iyasọtọ fun isinmi ilẹ wọn. Wọn kò gbọdọ gbin ohunkohun, eyi ti o ba si ṣẹlẹ hù tikara rẹ ni lati jẹ ti awọn alaini. Ni ọdun ikẹfa ire oko yoo pọ to bẹẹ gẹ ti anito yoo wa fun ọdun ti n bọ. Ṣugbọn a kò ri akọsilẹ pe awọn Ọmọ Israẹli pa ofin yii mọ́ lati jẹ ki ilẹ naa sinmi laaarin gbogbo ẹẹdẹgbẹta ọdun o din mẹwaa (490) ti wọn ti wà ni ominira. Yoo gba aadọrin ọdun lati ra gbogbo ọjọ isinmi ti wọn ti ṣe aika si pada, iye akoko gan an ti a sọ asọtẹlẹ rẹ̀ pe wọn o fi wà ninu igbekun.

Bi Ọlọrun ba ṣee ni ọran dandan gbọn lati ri i pe a mu ofin Rẹ̀ ṣẹ ninu awọn ẹ̀dá ti o da bi ẹnipe kò ni laari, melomelo ju bẹẹ lọ ni yoo fi dandan gbọn mu ọran igbala ọkàn wa! O ti ṣe ileri iye ainipẹkun fun gbogbo awọn ti wọn ba lo igbesi-ayé wọn gẹgẹ bi ẹ̀kọ́ Bibeli; ṣugbọn ijiya, ayeraye duro de awọn ti wọn kò lati tẹle ilana Rẹ̀, bi o tilẹ jẹ pe awọn eniyan kan n ṣe iwaasu "ọ̀rọ didun-didun" nipa sisẹ́ ọrun apaadi ayeraye.

**Ajaga Jeremiah**

Jeremiah ti gbé ajaga igi kan kọ́ ọrun rẹ̀ gẹgẹ bi ami lati ṣe apẹẹrẹ fun awọn Ju nipa kikó wọn lẹrú lọ si igbekun, lati maa rán wọn leti pe ajaga ọ̀tá wà ni ọrun wọn. Wọn wà ni itẹlọrun labẹ akoso Nebukadnessari niwọn igba ti wọn n ṣe ohun ti o wù u. Hananiah já ajaga igi naa kuro lati fi yé awọn eniyan pe isinrú wọn fẹrẹ de opin. Ẹtàn ni eyi. Ọlọrun si rán Jeremiah lati sọ pe: "Bayi li OLUWA awọn ọmọ-ogun, Ọlọrun Israẹli wi: emi ti fi ajaga irin si ọrùn gbogbo orilẹ-ède wọnyi, ki nwọn ki o sin Nebukadnessari, ọba Babeli, nwọn o si sìn i, emi si fi ẹranko igbẹ fun u pẹlu" (Jeremiah 28:14). Nitori iṣọtẹ wọn, isinrú awọn Ọmọ Israẹli yoo tun le koko jù bẹẹ lọ.

Nigba ti Nebukadnessari fi ogun yi Jerusalẹmu ká, awọn ara ilu kò ri ounjẹ jẹ mọ́. (Tẹlẹ wọn maa n saba ni anitó ounjẹ). Kò si ọ̀kan ninu awọn orilẹ-ède ti o yi wọn ká ti o wá ṣe iranlọwọ fun wọn. Wọn kò tilẹ lè wá, nitori Nebukadnessari ti ṣẹgun awọn tikara wọn pẹlu. Lẹyin eyi, awọn igba kan ti kọja sẹyin gẹge bi itan awọn Ọmọ Israẹli ti awọn pẹlu ti ṣẹgun awọn orilẹ-ède wọnni, nipa bẹẹ yoo jẹ ayọ̀ wọn pe akoko igbẹsan dé, bi o ba ṣeeṣe. Bayi ni a ri pe gbogbo aye kọ ẹ̀yin si awọn Ju, wọn si ni lati jẹ iya fun kíkọ̀ Ọlọrun silẹ ati sisin oriṣa.

**Awọn Wolii Oloootọ**

Ọlọrun fẹ ṣe awọn eniyan naa ni oore. O si ti rán awọn wolii ti o jẹ oloootọ ti wọn si n kilọ fun awọn eniyan ni ojoojumọ nipa idajọ. Ṣugbọn awọn eniyan "fi awọn onṣẹ Ọlọrun ṣe ẹlẹya, nwọn si kẹgan ọ̀rọ rẹ̀, nwọn si fi awọn woli rẹ̀ ṣẹsin, titi ibinu Oluwa fi ru si awọn enia rẹ̀, ti kò fi si atunṣẹ" (2 Kronika 36:16).

Ọlọrun sọ pe Oun yoo mú ki awọn Ọmọ Israẹli di "iyọṣuti si." Awọn orilẹ-ède miiran yoo rekọja lẹba ilẹ wọn wọn o si korira wọn pupọ to bẹẹ ti wọn o maa kẹgan awọn eniyan yii ti a mọ̀ ni ayanfẹ Ọlọrun. Wo bi yoo ti buru to fun ilẹ naa!

Yoo maa ya awọn alejo pẹlu lẹnu pe ki ni fa iru isọdahoro yii wá sori Israẹli. "Ọ̀pọlọpọ orilẹ-ède yio rekọja lẹba ilu yi, nwọn o wi, ẹnikan fun ẹnikeji rẹ̀ pe, Ẽṣe ti OLUWA ṣe bayi si ilu nla yi? Nigbana ni nwọn o dahùn pe, nitoriti nwọn ti kọ̀ majẹmu OLUWA Ọlọrun wọn silẹ; ti nwọn fi ori balẹ fun ọlọrun miran, nwọn si sin wọn" (Jeremiah 22:8, 9).

A kò wa laaye fun ara wa nikan. Awọn ẹlomiran n ṣọ́ igbesi-ayé wa. Bi a ba jẹ oloootọ ni si sin Ọlọrun, wọn n kiyesi i. Bi a ba si pẹyin dà, awọn ẹlẹṣẹ yoo mọ lẹsẹ kan naa yoo si yà wọn lẹnu pe ki ni o dé. Olukuluku apẹyinda ni n mu ẹgan bá orukọ Jesu. O ta abuku si ọ̀na Kristi. Alaanu ni Ọlọrun, O si n du u lati mú gbogbo ẹlẹṣẹ, ati awọn apẹyinda pẹlu, pada si ọdọ Rẹ̀. Ṣugbọn ọ̀pọlọpọ eniyan ni ifẹ ninu iṣẹ wọn, ilepa fun ọrọ̀ ati okiki to bẹẹ ti wọn kò ni akoko lati gbọ́ ti Ọlọrun.

Ọlọrun sọ fun awọn eniyan Juda pe, "Emi ti ba ọ sọ̀rọ ni igba ire rẹ̀; iwọ wipe, emi ki yio gbọ́. Eyi ni iwa rẹ lati igba ewe rẹ wá, ti iwọ kò si gba ohùn mi gbọ" (Jeremiah 22:21). Ọlọrun ti kilọ fun awọn eniyan Amẹrika to gẹgẹ bi O ti kilọ fun awọn eniyan igba Majẹmu Lailai, ṣugbọn ni igba ire wọn wọn kò ronu pe o yẹ lati ni Olugbala. Bi o tilẹ jẹ pe pupọ ni afara wé iwa-bi-Ọlọrun, wọn n lọ si ile-isin ni Ọjọ-ọsẹ, wọn kò ronupiwada ẹ̀ṣẹ wọn. Awọn eniyan kò sin oriṣa, ṣugbọn wọn n sin iṣẹ́ ọwọ ara wọn.

Ohun gbogbo ni wọn n dawọ le lati ṣe, lẹyin naa bi akoko ba kù, wọn le yọọda diẹ fun Ọlọrun. Nigba ti awọn eniyan ba dide duro ni idajọ, Ọlọrun yoo rán wọn leti ọ̀pọlọpọ ikilọ ti Oun fi fun wọn.

**A Pa Babiloni Run**

Ọlọrun lo Nebukadnessari lati mu idajọ wá sori Juda; ṣugbọn nikẹyin Nebukadnessari paapaa jiya, nitori ti kò fi ọlá fun Ọlọrun. Ijọba Babiloni gberu fun saa kan, ọgba ti Nebukadnessari ṣe si ofurufu si jẹ ọkan ninu awọn nnkan iyanu meje ti o wà ni aye igba naa. Ṣugbọn Ọlọrun sọ pe Oun yoo sọ Babiloni di "ahoro titi lai." Lọjọ oni Babiloni ilu alagbara ti o ni odi iṣẹpo meji ti o ga to ọdunrun ẹsẹ nigba kan, ti o ni ọgọta ilẹkun odi, awọn afara daradara, awọn mọṣalaṣi, tẹmpili oriṣiriṣi, awọn ọgba ati isun omi, wa labẹ ilẹ, panti ọpọlọpọ ọgọrun ọdun si ti bo o mọlẹ. Iba okiti alapa diẹ ni o duro lati tọka ibi ti olu-ilu nì atijọ wà.

**Aanu Ọlọrun**

Jeremiah sọkun pupọ nitori iṣẹ iparun ti o ni lati jẹ fun wọn, ṣugbọn sibẹ o tun ni lati mu awọn ẹrú wọnyi mọ pe ireti wà fun wọn. Lẹyin iya aadọrin ọdun, Ọlọrun yoo tun tẹti silẹ si adura wọn fun idasilẹ kuro ninu igbekun bi wọn o ba kepe E. "Ẹnyin o si kepe mi, ẹ o si lọ, ẹ o si gbadura si mi, emi o si tẹti si nyin. Ẹnyin o si ṣafẹri mi, ẹ o si ri mi, nitori ẹ o fi gbogbo ọkàn nyin wá mi" (Jeremiah 29:12, 13).

Iṣẹ kan naa ni a rán si awa naa lọjọ oni lati inu Ọrọ Ọlọrun. Bi awa ba fi gbogbo ọkàn wa ṣafẹri Olugbala wa, Oun yoo di riri fun wa. A kò le bo ẹ̀ṣẹ mọlẹ ki a ri ojurere Ọlọrun. Ṣugbọn bi a ba ronupiwada, ti a si jẹwọ, ki a si gbagbọ́, a o gbà wá là. Bakan naa ni ileri yii wà fun ẹnikẹni. "Ẹnikẹni ti o ba si fẹ, ki o gbà omi iye na lọfẹ" (Ifihan 22:17).

**AWỌN IBEERE**

1. Ta ni ọba Babiloni? Ki ni Ọlọrun pe e?
2. Ki ni ṣe ti kiko lọ si igbekun de ba Juda?
3. Ọdun meloo ni Ọlọrun sọ pe wọn o gbé ninu ikolọ?
4. Ki ni ofin Ọlọrun nipa isimi ilẹ?
5. Ki ni ṣe ti Jeremiah gbé ajaga igi kọ ọrun?
6. Ki ni itumọ ajaga irin?
7. Ki ni awọn wolii oloootọ sọ fun awọn Ọmọ Israẹli?
8. Ki ni ṣẹlẹ si Babiloni lẹyin ti a ti jẹ Israẹli niya?
9. Ki ni ireti ti Jeremiah fi fun awọn Ọmọ Israẹli?
10. Bawo ni a ṣe le ri Olugbala?